awọn ọmọbinrin olórin silẹ. (Jer 25:10; 2 Sam 19:35.)

5. Ati pẹlu ti wọn o bẹ̀rù ibi ti o ga, ti ìwárìrì yoo si wa ni ọ̀nà, ati ti igi almọndi yoo tanna, ti ẹlẹ́ngà yoo di ẹrù, ti ifẹ yoo si ṣá: nitori ti ọkunrin nlọ si ile rẹ̀ ayérayé, awọn aṣọ̀fọ̀ yoo si maa yide kakiri. (Job 17:13; Jer 9:17.)

6. Tabi ki okùn fàdákà to ja, tabi ki ọpọ́n wura tó fọ́, tabi ki iṣa to fọ nibi isun, tabi ki kẹkẹ to kán nibi kọnga,

7. Nigba naa ni erùpẹ̀ yoo pada si ilẹ̀ bi o ti wà ri, ẹmi yoo si pada tọ Ọlọrun ti o fi i fun ni. (Gen 3:19; Job 34:15; Psm 90:3; Job 34:14; Isa 57:16; Sek 12:1.)

8. Asán ninu asán, oniwaasu wi pe, gbogbo rẹ asán ni. (Onws 1:2.)

**Ọgbọn Ọlọrun ni o mu ki eniyan ri ìdí ohun ti o jinlẹ̀.**

9. Ati pẹlu, nitori Oniwaasu naa gbọn, o si nkọ awọn eniyan ni ìmọ̀ pẹlu; nitootọ o ṣe akiyesi daradara, o si wadi, o si fi owe pupọ lélẹ̀ ni ẹsẹsẹ. (1 A.Ọba 4:32.)

10. Oniwasu naa wadi lati ri ọ̀rọ̀ dídùn, pẹlu ni ìdúró ṣinṣin, o kọ ọ̀rọ̀ otitọ. (Owe 10:32; 22:20,21.)

**Ṣiṣe iyebiye ọ̀rọ̀ oniwaasu.**

11. Ọrọ ọlọgbọn dabi ẹ̀gún, ati gẹgẹ bi ìṣó ti a kàn, bẹẹ ni akojọ ọ̀rọ̀ ti a nfi fun ni lati ọwọ oluṣọ-agutan kan wa. (Onws 7:5; A.A. 2:37; Esra 9:8; Isa 22:23.)

12. Ati ṣiwaju, lati inu èyí, ọmọ mi, gba imọran: ninu kikọ iwe pupọ, opin ko si; ati iwe kika pipọ ni àárẹ̀ ara.

**Oniwaasu fẹ ki a mọ̀ pe a o mu gbogbo iṣẹ wá si ìdájọ́.**

13. Opin gbogbo ọrọ naa ti a gbọ ni pe: Bẹru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori èyí ni fun gbogbo eniyan. (Deut 4:2; Onws 8:5; Mika 6:8.)

14. Nitori pe Ọlọrun yoo mu olukuluku iṣẹ wa sinu ìdájọ́, ati olukuluku ohun ìkọ̀kọ̀, ibaa ṣe rere, ibaa ṣe buburu. (Matt 10:26; 12:36; 1 Kor 4:5.)

22

# ORIN SOLOMỌNI

**(B.C. 1014)**

ORI 1.

**Àkọlé.**

Orin awọn orin tí i ṣe ti Solomoni. (1 A.Ọba 4:32.)

**Ọkọ nreti Olùfẹ́ rẹ̀.**

2. Jẹ ki ó fi ìfẹnukonu ẹnu rẹ̀ kò mi ní ẹnu nitori ifẹ́ rẹ̀ sàn ju ọtí-waini lọ. (O.Sol. 4:10.)

3. Nitori ti oorun ìkunra rere rẹ̀, orúkọ rẹ̀ dabi ìkunra tí a tú jáde, nitori naa ni àwọn wúndíá ṣe fẹ́ ọ. (O.Sol. 4:10; Onws 7:1.)

4. Fà mi, àwa o sare tọ̀ ọ́: ọba ti mú mi wá sinu iyàrá rẹ̀: awa o yọ̀, inu wa yoo si dùn si ọ, awa yoo ranti ìfẹ́ rẹ ju ọti-waini lọ; wọn fẹ ọ nitootọ. (Psm 45:14,15.)

5. Emi dúdú, ṣugbọn mo ní ẹwà, Ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu, bi àwọn àgọ́ Kédárì, bi àwọn aṣọ-tita Solomoni. (O.Sol. 2:14; 4:3; 2:7; 5:8.)

6. Ma ṣe wò mi, nitori pé mo dúdú, nitori pé òòrùn ti bojuwo mi: awọn ọmọ ìyá mi binu si mi; wọn fi mi ṣe oluṣọ ọgbà-àjàrà; ṣugbọn ọgbà-àjàrà tèmi ni èmi kò tọju. (Psm 69:8; O.Sol. 8:11.)

7. Wi fun mi, Ìwọ ẹni tí ọkàn mí fẹ́, ni ibi ti iwọ nsọ́ agutan; ni ibi ti iwọ

nmu agbo-ẹran rẹ sinmi ni ọsán; ki emi ma baa dabi aláàrẹ̀ ti o ṣìnà kiri pẹlu agbo-ẹran àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀. (O.Sol. 3:1–4; 2:16; 8:13.)

8. Bi iwọ kò bá mọ̀, iwọ arẹwà jùlọ ninu awọn obinrin, jade lọ nipasẹ agbo-ẹran, ki iwọ si bọ́ awọn ọmọ ewurẹ rẹ lẹba àgọ́ awọn olùṣọ́-àgùtàn. (O.Sol. 5:9; 6:1.)

**Ọkọ pẹlu iyawo rẹ̀.**

9. Olufẹ mi, mo ti fi ọ wé ẹṣin mi ninu kẹ̀kẹ́ Farao. (O.Sol. 2:2,10,13; 2 Kro 1:16.)

10. Ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ wuni ninu ohun-ọ̀ṣọ́, ọrùn rẹ ninu ìlẹ̀kẹ̀. (5:13.)

11. Awa o ṣe ohun-ọ̀ṣọ́ wura fun ọ, pẹlu àmì fadaka.

12. Nigba ti ọba wà ni ibùjókòó tábìlì rẹ̀, òróró mi rán òórùn rẹ̀ jade.

13. Idí ojia ni olùfẹ́ ọ̀wọ́n mi sí mi; oun o maa gbe aarin ọmú mi.

14. Olùfẹ́ mi rí si mi bi ìdí ìtànná igi Kipressi ni ọgbà-ajara Engedi. (O.Sol. 4:13.)

15. Wo o, iwọ lẹwa, olùfẹ́ mi, wo o, iwọ lẹ́wà: iwọ ní ojú àdàbà. (O.Sol. 4:1; 5:12.)

16. Wo o, iwọ lẹ́wà, olufẹ mi, nitootọ, ó wu ni: ibùsùn wa pẹ̀lú ni itura.

17. Igi kedari ni ìtí-igi ile wa, igi firi si ni ẹkẹ́ wa. (1 A.Ọba 6:9,10; 2 Kro 3:5.)

## ORI 2.

EMI ni ìtànná eweko Sárónì, ati ìtànná lílì awọn àfónífojì. (Isa 35:1,2; O.Sol. 5:13; 7:2.)

2. Bi ìtànná lílì laarin ẹ̀gún, bẹẹ ni olufẹ mi ri laarin àwọn ọmọbìnrin.

3. Bi igi eleso laarin awọn igi ìgbẹ́, bẹẹ ni olufẹ mi ri laarin awọn ọmọkunrin. Emi fi ayọ̀ nla jókòó labẹ òjìji rẹ̀, èso rẹ̀ si dun mọ mi lẹnu. (O.Sol. 8:5; 4:13.)

4. O mu mi wa si ile ọti-waini, Ifẹ si ni ọ̀págun rẹ̀ lori mi. (Psm 20:5.)

5. Fi àkàrà dídùn da mi duro, fi eso igi tù mi ni inú: nitori àìsàn ifẹ́ nṣe mi. (O.Sol. 7:8; 5:8.)

6. Ọwọ́ òsì rẹ̀ nbẹ labẹ orí mi, ọwọ́ ọ̀tún rẹ si gbà mi mọ́ra. (O.Sol. 8:3.)

7. Mo fi awọn abo egbin, ati awọn abo àgbọ̀nrin ìgbẹ́ fi yín bú, ẹyin ọmọbìnrin Jerusalẹmu, ki ẹ ma ṣe ru olùfẹ́ mi soke, ki ẹ ma si ṣe ji i, titi yoo fi wu u. (O.Sol. 3:5; 8:4.)

**Ìyìn obinrin rẹ̀ ní ọ̀sán.**

8. Ohùn olufẹ mi! Sa wo o, o nbọ, o nfò lori áwọn òkè, o nbẹ lori awọn òkè kékèké. (ẹsẹ 17.)

9. Olùfẹ́ mi dabi abo egbin, tabi ọmọ àgbọ̀nrín: sa wo o, o duro lẹhìn ogiri wa, o yọju loju fèrèsé, o nfi ara rẹ̀ hàn loju fèrèsé ọlọ́nà. (ẹsẹ 17.)

10. Olùfẹ́ mi sọ̀rọ̀, o si wi fún mi pé, "Dìde, olùfẹ́ mi, arẹwà mi kannaa, ki o si jade káłọ. (ẹsẹ 13.)

11. Sa wo o, ìgbà ọ̀tútù ti kọjá, òjò ti dá, o si ti lọ.

12. Awọn ìtànná ewéko farahàn lori ilẹ̀; àkókò ìkọrin awọn ẹyẹ dé, a si gbọ́ ohùn àdàbà ni ilẹ̀ wa. (Psm 74:19.)

13. Igi ọ̀pọ̀tọ́ so èso titun, awọn àjàrà funni ni òórùn daradara nipa ìtànná wọn, Dide, olufẹ mi, arẹwà mi kannaa, ki o si jade kalọ. (Matt 24:32.) O.Sol. 7:12; ẹsẹ 10.)

14. Àdàbà mi, ti o wa ninu pàlàpálá òkúta, ni ibi ìkọ̀kọ̀ òkuta, jẹ ki emi ri ojú rẹ, jẹ ki emi gbọ ohùn rẹ; nitori didun ni ohùn rẹ, oju rẹ si lẹ́wà!" (O.Sol. 5:2; Jer 48:28; O.Sol. 8:13; 1:5.)

15. Mu awọn kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ wa fun wa, awọn kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ kékeké ti nba àjàrà jẹ́: nitori àjàrà wa ní ìtànná. (Esk 13:4.)

16. Olufẹ mi ni temi, emi si ni tirẹ̀: o njẹ laarin awọn lili. (O.Sol. 6:3; 7:10.)

17. Titi igba itura ọjọ́, titi òjìji yoo fi sálọ, yipada, olufẹ mi, ki iwọ si dabi abo egbin, tabi ọmọ àgbọ̀nrín lori awọn òkè Beteri. (O.Sol. 4:6; ẹsẹ 8,9.)

## ORI 3.

**Ìyìn obinrin rẹ̀ ni òru.**

NI òru lori àketè mi, mo wá ẹni ti ọkàn mi fẹ: emi wa a ṣugbọn emi ko ri i. (Isa 26:9; O.Sol. 1:7; 5:6.)

2. "Emi o dide ni isinsinyìí, emi o si rìn lọ si ilu, ni igboro, ati ni ita-ilu ni emi o wa ẹni ti ọkàn mi fẹ́." Emi wa a, ṣugbọn emi ko rii. (Jer 5:1.)

3. Awọn olùṣọ́ ti nrin ilu yika ri mi: mo bẹ̀ẹ̀rè pe, "Ẹ ha ri ẹni ti ọkàn mi nfẹ bí?" (O.Sol. 5:7.)

4. Ṣugbọn bi mo ti fi wọn silẹ gẹ́rẹ́ ni mo ri ẹni ti ọkan mi fẹ́: mo di i mu, emi ko si fi silẹ, titi mo fi mu un wa sinu ile ìyá mi, ati sinu iyàrá ẹni ti o loyun mi. (O.Sol. 8:2.)

5. Mo fi awọn abo egbin ati awọn abo àgbọ̀nrín ìgbẹ́ fi yin bú, ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu, ki ẹ má ṣe ru olùfẹ́ mi soke, ki ẹ ma si ji i, titi yoo fi wu u. (O.Sol. 2:7; 8:4.)

**Ọkọ iyawo dé.**

6. Tani eyi ti nti ijù jáde wa bi ọ̀wọ̀n èéfín, ti a ti fi ojia ati tùràrí kun lara, pẹlu gbogbo àtíkè olóorùn ti onìṣòwò? (O.Sol. 8:5; 1:13; 4:6,14.)

7. Wo akete rẹ, ti i ṣe ti Solomọni; ọgọta akọni eniyan ni o yi i ka ninu awọn akọni Israẹli.

8. Gbogbo wọn ló di idà mu, wọn gbọ́n ọgbọ́n ogun: olukuluku kó idà rẹ̀ nitori ẹrù ni òru. (Jer 50:9; Psm 45:3; 91:5.)

9. Solomoni, ọba ṣe akete nla fun ara rẹ̀ lati inu igi Lebanọni.

10. O fi fàdákà ṣe ọ̀wọ̀n rẹ̀, o fi wura ṣe ibi ẹhin rẹ̀, o fi elése àlùkò ṣe ibùjókòó rẹ̀, inú rẹ̀ ni o fi ifẹ tẹ́ nitori awọn ọmọbinrin Jerusalẹmu. (O.Sol. 1:5.)

11. Ẹ Jade lọ, Ẹyin ọmọbinrin Sioni, ki ẹ si wo Solomoni, ọba, oun pẹlu adé ti ìyá rẹ̀ fi de e lọjọ igbeyawo rẹ̀, ati lọjọ ayọ̀ ọkàn rẹ̀. (O.Sol. 3:16,17.)

## ORI 4.

**Ọ̀rọ̀ ìfẹ́.**

WO o, ìwọ lẹ́wà, olùfẹ́ mi: wo o, ìwọ lẹ́wà; iwọ loju àdàbà labẹ ìbòjú rẹ: irun rẹ dabi ọ̀wọ́ ewurẹ, ti o dùbúlẹ̀ lori òkè Gileadi. (O.Sol. 1:15; 5:12; 6:5,7.)

2. Ehín rẹ dabi ọ̀wọ́ ewurẹ ti a rẹ́ ni irun, ti o gokẹ lati ibi iwẹ̀ wá, olukuluku wọn bi ìbejì, kò si sí ọ̀kan ti o yàgàn ninu wọn. (O.Sol. 6:6.)

3. Ètè rẹ dabi òwú òdòdó, ohùn rẹ si dùn: ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ si dabi ẹ̀là pomegranate kan labẹ ìbojú rẹ. (O.Sol. 6:7.)

4. Ọrùn rẹ dabi ile-ìṣọ́ Dafidi ti a kọ́ fún ìhámọ́ra, lori eyi ti a fi ẹgbẹ̀rún àpáta kọ́, gbogbo wọn jẹ́ asà awọn alagbara. (O.Sol. 7:4; Neh 3:19.)

5. Ọmú rẹ̀ mejeji dabi abo egbin kékeré meji ti i ṣe ìbejì, ti njẹ̀ laarin ìtànná lílì. (O.Sol. 7:3; 2:16; 6:2,3.)

6. Títí ọjọ́ yoo fi rọ̀, ti òjìji yoo si fi fò lọ, emi o lọ si òkè nla òjìá, ati si òkè kékeké turari. (O.Sol. 2:17; ẹsẹ 14.)

7. Ìwọ́ ní ẹwà gbogbo, olùfẹ́ mi; kò si àbàwọ́n lara rẹ! (O.Sol. 1:15.)

8. Jade wa pẹlu mi kuro ni Lebanọni, iyawo mi, jade wá pẹlu mi kuro ni Lebanọni: wò lati orí òkè Amana, lati orí òkè Seniri ati Hermoni, lati ibi ihò kinniun, lati òkè awọn ẹkùn. (O.Sol. 5:1; Deut 3:9.)

9. Ìwọ ti gbà mi lọ́kàn, arabinrin mi, iyawo! iwọ ti fi ìwò oju rẹ kan, ati ọ̀kan ninu ẹ̀wọ̀n ọrùn rẹ gba mi lọ́kàn. (ẹsẹ 10,12; Owe 1:9; Esk 16:11.)

10. Ìfẹ́ rẹ ti dára tó, arabinrin mi, iyawo! ifẹ rẹ ti san ju ọti-waini to! òórùn ikunra rẹ si ju tùràrí gbogbo lọ. (O.Sol. 1:3–4.)

11. Iyawo! ètè rẹ nkán bi afáráoyin: oyin ati wàrà nbẹ labẹ ahọ́n rẹ; òórùn aṣọ rẹ si dabi òórùn Lebanọni. (Owe 5:3; 24:13; Gen 27:27; Hos 14:6.)

12. Ọgba ti a ṣe ni arabinrin mi, iyawo! ìsun ti a sé, orisun ti a fi èdìdí dí. (Owe 5:15–18; Owe 29:3.)

13. Ohun gbíngbìn rẹ agbala pomegranate ni, pẹlu èso ti o wu ni; kipressi ati nardi. (Onws 2:5; O.Sol. 6:11; 7:12; ẹsẹ 16; O.Sol. 1:14.)

14. Nardi ati saffroni; kálámúsì, kinnamọni, pẹlu gbogbo igi turari ojia ati aloe, pẹlu gbogbo awọn olori oloorun dídùn. (O.Sol. 1:12; Eks 30:23; ẹsẹ 6; O.Sol. 3:6; Jhn 19:39.)

15. Orisun ninu ọgba kọ̀nga omi ìyè, ti nṣan lati Lebanọni wá. (Jhn 4:10; 7:38.)

16. Ji afẹ́fẹ́ ariwa; si wa, iwọ ti gusu; fẹ́ sori ọgbà mi, ki oorùn inu rẹ le fẹ jade. Jẹ ki olùfẹ́ mi wa sinu ọgbà rẹ̀, ki o si jẹ eso dídára rẹ̀. (O.Sol. 5:1; 6:2.)

ORI 5.

MO dé inú ọgbà mi, arábìnrin mi iyawo! mo ti ko ojia mi pẹlu òórùn dídùn mi jọ; mo ti jẹ afárá mi pẹlu oyin mi; mo ti mu ọti-waini mi pẹlu wàrà mi: Ẹ jẹun, ẹ̀yin ọ̀rẹ́; mu, àní mu àmuyó, ẹyin olufẹ. (O.Sol. 6:2; 4:9,11,14; Luk 15:7,10; Jhn 3:29.)

**Àlá rẹ̀ da ọkàn rẹ̀ laamu.**

2. Emi sun, ṣugbọn ọkan mi ji, ohùn olùfẹ́ mi ni nkànkùn, wi pe, "Ṣi ìlẹ̀kùn fun mi, arábìnrin mi, olùfẹ mi, àdàbà mi, alailabawọn mi: nitori orí mi kun fun ìrì, ati ìdì irun mi fun kíkan rẹ." (O.Sol. 4:9; 6:9; ẹsẹ 11.)

3. Mo ti bọ ẹ̀wù mi; emi o ti ṣe gbe e wọ̀? Mo ti wẹ ẹsẹ̀ mi, emi o ti ṣe sọ wọn di àìmọ́? (Luk 11:7; Gen 19:2.)

4. Olùfẹ́ mi nawọ́ rẹ̀ lati inu ihò ìlẹ̀kùn, inú mi yọ́ sii.

5. Emi dide lati ṣílẹ̀kùn fun olùfẹ́ mi, ojia si nkan lọwọ mi, ati ojia oloorun dídùn ni ìka mi sori idabu ilẹkùn. (ẹsẹ 13.)

6. Mo ṣílẹ̀kùn fun olùfẹ́ mi; ṣugbọn olùfẹ́ mi ti fà sẹ́hìn, o si ti lọ: àyà pa mi nígbà tí o sọ̀rọ̀, mo wa a, ṣugbọn emi ko ri i, mo pè é, ṣugbọn oun ko dá mi lohùn.

7. Awọn olùṣọ́ ti nrin ilu kiri rí mi, wọn lu mi, wọn si ṣa mi lọ́gbẹ́, awọn olùṣọ́ gba ìborùn mi lọ́wọ́ mi. (O.Sol. 3:3.)

8. Mo fi yín bu, ẹ̀yin ọmọbìnrin Jerusalẹmu, bi ẹ̀yín ba ri olùfẹ́ mi, ki ẹ wi fun un pé, aisan ífẹ́ nṣe mi. (O.Sol. 2:7; 3:5; 2:5.)

9. Kinni olufẹ rẹ fi ju olufẹ miran lọ, ìwọ arẹwà julọ ninu àwọn obinrin? Kinni olufẹ rẹ fi ju olufẹ miran ti ìwọ fi nfi wa bú bẹ̃? (O.Sol. 1:8; 6:1.)

10. Olùfẹ mi funfun, o si pọ́n, oun ni ọlá ju ọ̀pọ̀lọpọ̀ lọ.

11. Orí rẹ̀ dabi wura ti o dara julọ, ìdí irun rẹ̀ dabi imọ̀ ọ̀pẹ, o si dú bi ẹyẹ-ìwò.

12. Ojú rẹ̀ dabi ẹyẹ àdàbà lẹba odò, ti a fi wàrà wẹ̀, ti o si ngbe inu alaafia. (O.Sol. 1:15; 4:1.)

13. Ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀ dabi ebè turari, bi oloorun dídùn, ètè rẹ̀ bi itanna lílì, o nkan ojia oloorun dídùn. (O.Sol. 6:2; 2:1.)

14. Ọwọ́ rẹ̀ dabi oruka wúrà ti o tò ni bẹrili yíká; ara rẹ̀ bi ehín-erin dídán ti a fi saffire bò.

15. Itan rẹ̀ bi ọ̀wọ̀n marbili, ti a gbe ka ihò ìtẹ̀bọ́ wura dáradára; ìwò rẹ̀ dabi Lebanoni, titayọ rẹ̀ bi igi kedari.

16. Ẹnu rẹ̀ dun rekọja; ani o wuni patapata, Eyi ni olufẹ mi, eyi si ni ọ̀rẹ́ mi, ẹ̀yin ọmọbìnrin Jerusalẹmu. (O.Sol. 7:9; 2 Sam 1:23.)

ORI 6.

NIBO ni olùfẹ́ rẹ lọ, iwọ arẹwà julọ ninu àwọn obinrin? Nibo ni olùfẹ́ rẹ yà sí? Ki a le ba ọ wa a. (O.Sol. 5:6; 1:8.)

2. Olùfẹ́ mi sọkalẹ lọ sinu ọgbà rẹ̀, si ebè tùràrí, lati maa jẹ ninu ọgbà, ati lati ka ìtànná lílì. (O.Sol. 4:16; 5:1,13; 1:7; 2:1.)

3. Emi ni ti olùfẹ́ mi, olùfẹ́ mi si ni tèmi: o njẹ laarin itanna lílì. (O.Sol. 2:16; 7:10.)

**Ẹ̀rò àtọkànwá ti ọkọ ìyàwó rò nipa olùfẹ́ rẹ̀.**

4. Iwọ yanjú, olùfẹ́ mi, bi Tirsa, ó lẹ́wà bi Jerusalẹmu, ṣugbọn o lẹ́rù bi ogun pẹlu ọ̀págun. (O.Sol. 1:15; ẹsẹ 10.)

5. Mu ojú rẹ kuro lara mi nitori wọn borí mi: irun rẹ̀ si dabi ọwọ́ ewurẹ ti o dùbúlẹ̀ ni Gileadi. (O.Sol. 4:1.)

6. Ehín rẹ dabi ọ̀wọ́ àgùtàn ti ngoke lati ibi ìwẹ̀ wá, ti olukuluku wọn bi

ìbejì, ko sì sí ọ̀kan ti o yàgàn ninu wọn. (O.Sol. 4:2.)

7. Bi ẹ̀là èso-pomegranate kan ni ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀ rí laarin iboju rẹ̀. (O.Sol. 4:3.)

8. Ọgọta ayaba ni nbẹ, ati ọgọrin àlè, ati awọn wundia lainiye. (1 A.Ọba 11:3; O.Sol. 1:3.)

9. Ọ̀kan ni ẹyẹ àdàbà mi, alailabawọn mi; oun nikanṣoṣo ni ti iya rẹ̀, oun ni ààyò ẹni tí o bi i. Awọn ọmọbìnrin ri i, wọn si súre fun un, àní awọn ayaba ati awọn àlè, wọn si yìn ín. (O.Sol. 2:14; 5:2; Gen 30:13.)

10. "Tani ẹni ti ntàn jade bi òwúrọ̀, ti o lẹ́wà bi ọ̀ṣùpá, ti o mọ́ bi oorùn, ti o si lẹ́rù bi ogun pẹlu ọ̀págun?" (ẹsẹ 4.)

11. Emi sọkalẹ lọ sínú ọgbà eso igi, lati ri awọn ẹ̀ka igi tútù àfonífojì ati lati wo bi àjàrà bá rúwé, ati bi igi-pomegranate ba rudi. (O.Sol. 7:12.)

12. Ki emi to mọ̀, ọkàn mi gbé mi ka orí kẹ̀kẹ́ Amminadibu.

13. Pada, pada, Sulamite; pada, pada, ki awa baa le wo o, Eeṣe ti ẹ̀yin fẹ wo Sulamite bi ẹni pe orin ijọ Mahanaimu. (Ondj 21:21; Gen 32:2.)

## ORI 7.

ESẸ̀ rẹ ti lẹ́wà to ninu bàtà, iwọ ọmọ-aládé! Orike itan rẹ̀ dabi ohun ọṣọ́, iṣẹ ọwọ́ ọlọ́gbọ́n oníṣọ̀nà. (Psm 45:13.)

2. Ìwò rẹ̀ dabi ago ti kò ṣe alaini ọti, ara rẹ dabi òkìtì àlìkámà ti a fi lílì yika.

3. Ọmú mejeji dabi abo ọmọ àgbọ̀nrin meji ti i ṣe ibeji. (O.Sol. 4:5.)

4. Ọrùn rẹ̀ dabi ile ìṣọ ehín-erin; oju rẹ dabi adagún Hesboni, lẹba ẹnubode Batrabbimu: imú rẹ dabi ilé-iṣọ́ Lebanoni ti o kọju si ìhà Damasku. (O.Sol. 4:4.)

5. Orí rẹ dabi Karmeli lara rẹ, ati irun orí rẹ bi purpili; a fi àìdì irun rẹ̀ di ọba nigbèkùn (Isa 35:2.)

6. O ti lẹwa tó, o si ti dára tó, iwọ olufẹ mi ninu adùn ìfẹ́! (O.Sol. 1:15, 16.)

7. Iduro rẹ yìí dabi igi ọ̀pẹ ati ọmu rẹ bi ṣiri èso àjàrà.

8. Mo ni, emi o gun ọ̀pẹ lọ, emi o di ẹ̀ka rẹ̀ mu: pẹlupẹlu ni isinsinyìí ọmú rẹ pẹlu yoo dabi ṣírí àjàrà, ati òórùn imu rẹ̀ bi èso appili; (O.Sol. 2:5.)

9. Ati ẹnu rẹ bi ọti-waini ti o dárajù, ti o sọkalẹ kẹlẹkẹlẹ fun olùfẹ́ mi, ti o mu ki ètè awọn ti o sun sọ̀rọ̀.

**Ìyawo rẹ̀ fi ifẹ́ rẹ̀ fun un.**

10. Ti olùfẹ́ mi lemi nṣe, ìfẹ́ rẹ̀ si nbẹ si mi. (O.Sol. 2:16; 6:3; Psm. 45:11.)

11. Wa, olùfẹ́ mi, jẹ ki a lọ si pápá; jẹ ki a wọ̀ si awọn ìletò.

12. Jẹ ki a dide lọ sinu ọgbà-Àjàrà ni kùtùkùtù; jẹ ki a wo bi àjàrà ba rúwé, bi ìtànná àjàrà ba là, ati bi igi pomegranate ba rúdì: nibẹ ni emi o fi ìfẹ́ mi fun ọ. (O.Sol. 6:11.)

13. Awọn èso mandraki funni ni òórùn, ni ẹnu-ọ̀nà wa ni oniruuru eso ti o wuni, ọ̀tun ati ogbologbo, ti mo ti fi pamọ́ fun ọ, iwọ olùfẹ́ mi. (Gen 30:14; O.Sol. 2:3; 4:13,16.)

## ORI 8.

IWỌ iba jẹ́ dàbi arakunrin fun mi, ti o mu ọmú ìyá mi! emi iba ri ọ lode emi iba fi ẹnu kò ọ lẹnu; lootọ wọn kìibá fi mi ṣe ẹlẹ́yà.

2. Emi ìbá fọ̀nà hàn ọ́, emi iba mu ọ wá sinu ilé iyá mi ti o kọ́ mi; emi ìbá mú ọti-waini olóòórùn dídùn ati omi èso pomegranate mi. (O.Sol 3:4.)

3. Ọwọ́ osi rẹ iba wa labẹ orí mi, ọwọ́ ọ̀tún rẹ iba sì gbá mi mọ́ra. (O.Sol. 2:6.)

4. Mo fi yín bú, ẹyin ọmọbìnrin Jerusalẹmu, ki ẹ má ṣe rú olùfẹ́ mi sókè, ki ẹ má sì ṣe ji i, titi yoo fi wu u. (O.Sol. 2:7; 3:5.)

**Ẹwà ìfẹ́.**

5. Tani eyi ti ngòkè lati aginjù wá, ti o fi ara ti olùfẹ́ rẹ̀? Mo ji ọ dide labẹ igi eleso: nibẹ ni ìyá rẹ gbe bi ọ sí, nibẹ ni ẹni ti o bi ọ gbe bi ọ sí. (O.Sol. 3:6; 2:3.)

6. Gbe mi ka àyà rẹ bi èdìdí, bi èdìdí, le apa rẹ: nitori ifẹ lágbára bi ikú; ìjòwú si le bi iboji; jíjò rẹ dabi jíjò iná, ani ọwọ́ iná Oluwa. (Isa 49:16; Jer 22:24; Hag 2:23; Owe 6:34.)

7. Omi pupọ kò lè paná ifẹ, bẹẹ ni ìkún-omi kò lè gbá a lọ, bi eniyan fẹ fi gbogbo ọrọ̀ ile rẹ fun ifẹ, a o kẹ́gàn rẹ patapata.

8. Awa ni arabinrin kékeré kan, oun kò sì ni ọmú: kinni àwa o ṣe fun arabinrin wa lọjọ ti a o ba fẹ ẹ?

9. Bi oun ba ṣe ogiri, àwa o kọ́ ilé-odi fadaka le e lori: bi oun ba sì ṣe ẹnu-ọ̀nà, awa o fi pako kédárì di i.

10. Ogiri ni mi, ọmú mi si dabi ilé-iṣọ́; nigba naa ni mo dabi ẹni ti o rí ojúrere ni ojú rẹ.

11. Solomọni ni ọgbà-àjàrà kan ni Baalhamoni: o fi ọgbà-àjàrà naa ṣe ọ̀yà fun awọn olùṣọ́: olukuluku ni timu ẹgbẹrun fàdákà wa nipò èso rẹ. (Onws 2:4; Matt 21:33; O.Sol. 1:6; 2:3; Isa 7:23.)

12. Ọgbà-àjàrà mi, ti i ṣe tèmi, o wà ni iwaju mi: iwọ Solomoni yoo ni ọ̀yà ẹgbẹ̀rún fàdákà, ati awọn ti nṣọ èso naa yoo ni igba.

13. Iwọ ti ngbe inu ọgbà, awọn ẹgbẹ́ rẹ fetísí ohun rẹ: mu mi gbọ pẹlu. (O.Sol. 1:7; 2:14.)

14. Yára, olùfẹ́ mi, ki iwọ si dabi abo egbin tabi ọmọ àgbọ̀nrín lori òkè òórùn dídùn. (O.Sol. 2:17; 4:6.)

23

# WOLI ISAIAH

**(B.C. 769–698)**

ORI 1.

**Iṣọtẹ ti a fi idajọ ati oore-ọfẹ kò loju.**

IRAN Isaiah ọmọ Amosi, ti o ri nipa Juda ati Jerusalẹmu lọjọ Ussah, Jotamu, Ahasi, ati Hesekiah, awọn ọba Juda. (Num 12:6; Isa 2:1; 2 A.Ọba 15:1,13,32; 16:1; 18:1.)

**Àìlọ́pẹ́ Juda.**

2. Gbọ, ẹyin ọrun, si fi eti silẹ̀, iwọ ayé: nitori Oluwa ti sọ̀rọ̀, Awọn ọmọ ni emi ti tọ́ ti mo si mu dàgbà, ṣugbọn ti wọn ti ṣọ̀tẹ̀ si mi. (Deut 23:1.)

3. Malu mọ oluwa rẹ, kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ si mọ ibujẹ oluwa rẹ: ṣugbọn Israeli kò mọ̀, awọn eniyan mi kò ronú. (Jer 8:7; 9:3,6.)

4. A! Orilẹ-èdè ti o kun fun ẹ̀ṣẹ̀, eniyan ti ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ npa, iru awọn oluṣe buburu, awọn ọmọ ti i ṣe olubàjẹ́: wọn ti kọ Oluwa silẹ̀, wọn ti mu Ẹni-Mímọ́ Israeli binu, wọn si ti yipada sẹhìn. (Isa 14:20; ẹsẹ 28; Isa 5:24.)

5. Eeṣe ti a o fi lù yin si i, ti ẹyin o maa ṣọ̀tẹ̀ síwájú? Gbogbo orí ni o nṣaisan, gbogbo ọkàn ni o si dákú. (Isa 31:6; 33:24.)

6. Lati àtẹ́lẹsẹ̀ titi fi de orí kò si ilera ninu rẹ; bikoṣe ọgbẹ, ipalara, ati òjú ti nra: wọn kòì tíì pajúmọ́, bẹẹ ni a kòì tíì dí wọn, bẹẹ ni a kò ì sì tíì fi òróró kun wọn. (Job 2:7; Psm 38:3; Isa 30:26; Luk 10:34.)

7. Awọn ìgbèríko ilẹ yin di ahoro, a fi iná sun ilu olódi yin: ilẹ yin, ni alejo jẹ run loju yin, o si di ahoro, bi eyi ti awọn alejo wó lulẹ̀; (Isa 6:11; Jer 44:6.)

8. Ọmọbinrin Sioni, ni a si fi silẹ bi àgọ́ ninu ọgbà ajara, bi abúlé ninu ọgba apálá, bi ilu ti a dótì. (Job 27:18.)

9. Bikoṣe bi Oluwa awọn ọmọ-ogun ti fi iyoku diẹ kiun silẹ̀ fun wa, awa iba ti dàbí Sodomu, awa iba si ti dàbí Gomorra. (Rom 9:29; Isa 10:20–22.)

6. Gbe mi ka àyà rẹ bi èdìdí, bi èdìdí, le apa rẹ: nitori ifẹ lágbára bi ikú; ìjòwú si le bi iboji; jíjò rẹ dabi jíjò iná, ani ọwọ́ iná Oluwa. (Isa 49:16; Jer 22:24; Hag 2:23; Owe 6:34.)

7. Omi pupọ kò lè paná ìfẹ́, bẹẹ ni ìkún-omi kò lè gbá a lọ, bi eniyan fẹ fi gbogbo ọrọ̀ ile rẹ̀ fun ifẹ, a o kẹ́gàn rẹ̀ patapata.

8. Awa ni arabinrin kékeré kan, oun kò si ni ọmú: kinni àwa o ṣe fun arabinrin wa lọjọ ti a o ba fẹ ẹ?

9. Bi oun ba ṣe ogiri, àwa o kọ́ ile-odi fadaka le e lori: bi oun ba sì ṣe ẹnu-ọ̀nà, awa o fi pako kédárì di i.

10. Ogiri ni mi, ọmú mi si dabi ilé-iṣọ́; nigba naa ni mo dabi ẹni ti o ri ojúrere ni ojú rẹ.

11. Solomọni ni ọgbà-àjàrà kan ni Baalhamoni: o fi ọgbà-àjàrà naa ṣe ọ̀yà fun awọn olùṣọ́: olukuluku ni imu ẹgbẹrun fàdákà wa nipò èso rẹ̀. (Onws 2:4; Matt 21:33; O.Sol. 1:6; 2:3; Isa 7:23.)

12. Ọgbà-àjàrà mi, ti i ṣe tèmi, o wà ni iwaju mi: iwọ Solomoni yoo ni ọ̀yà ẹgbẹrun fàdákà; ati awọn ti nṣọ èso naa yoo ni igba.

13. Iwọ ti ngbe inu ọgbà, awọn ẹgbẹ́ rẹ fetísí ohun rẹ: mu mi gbọ pẹlu. (O.Sol. 1:7; 2:14.)

14. Yára, olùfẹ́ mi, ki iwọ si dabi abo egbin tabi ọmọ àgbọ̀nrín lori òkè òórùn dídùn. (O.Sol. 2:17; 4:6.)

23

# WOLI ISAIAH

**(B.C. 769–698)**

## ORI 1.

**Ìṣọ̀tẹ̀ ti a fi idajọ ati oore-ọfẹ kọ̀ lojú.**

IRAN Isaiah ọmọ Amosi, ti o ri nipa Juda ati Jerusalẹmu lọjọ Ussah, Jotamu, Ahasi, ati Hesekiah, awọn ọba Juda. (Num 12:6; Isa 2:1; 2 A.Ọba 15:1,13,32; 16:1; 18:1.)

**Àìlópẹ́ Juda.**

2. Gbọ, ẹyin ọrun, si fi eti sílẹ̀, iwọ ayé: nitori Oluwa ti sọ̀rọ̀, Awọn ọmọ ni emi ti tọ́ ti mo si mu dàgbà, ṣugbọn ti wọn ti ṣọ̀tẹ̀ si mi. (Deut 23:1.)

3. Malu mọ oluwa rẹ̀, kẹ̀tẹ́kẹ̀tẹ́ si mọ ibujẹ oluwa rẹ̀: ṣugbọn Israeli kò mọ̀, awọn eniyan mi kò ronú. (Jer 8:7; 9:3,6.)

4. A! Orilẹ-èdè ti o kun fun ẹ̀ṣẹ̀, eniyan ti ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ npa, iru awọn oluṣe buburu, awọn ọmọ ti i ṣe olubàjẹ́: wọ́n ti kọ Oluwa silẹ̀, wọn ti mu Ẹni-Mímọ́ Israeli binu, wọn si ti yipada sẹ̀hìn. (Isa 14:20; ẹsẹ 28; Isa 5:24.)

5. Eeṣe ti a o fi lù yin si i, ti ẹyin o maa ṣọ̀tẹ̀ síwájú? Gbogbo orí ni o nṣaisan, gbogbo ọkàn ni o si dákú. (Isa 31:6; 33:24.)

6. Lati àtẹ́lẹsẹ̀ titi fi de orí kò si ilera ninu rẹ̀; bikoṣe ọgbẹ, ipalara, ati òjú ti nra: wọn kòì tíì pajúmọ́, bẹẹ ni a kòì tíì dí wọn, bẹẹ ni a kò ì sì tíì fi òróró kun wọn. (Job 2:7; Psm 38:3; Isa 30:26; Luk 10:34.)

7. Awọn ìgbèríko ilẹ yin di ahoro, a fi iná sùn ilu olódi yin: ilẹ yin, ni alejo jẹ run loju yin, o si di ahoro, bi eyi ti awọn alejo wó lulẹ̀; (Isa 6:11; Jer 44:6.)

8. Ọmọbinrin Sioni, ni a si fi silẹ bi àgọ́ ninu ọgbà ajara, bi abúlé ninu ọgba apálá, bi ilu ti a dótì. (Job 27:18.)

9. Bikoṣe bi Oluwa awọn ọmọ-ogun ti fi iyoku diẹ kiun silẹ̀ fun wa, awa iba ti dàbí Sodomu, awa iba si ti dàbí Gomorra. (Rom 9:29; Isa 10:20–22.)